ELETI OFE

A-NJU-WON KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 843 LAGOS SATURDAY OCTOBER 27 – NOVEMBER 2 1962 KỌBỌ MEJI (2D)

**Ire Wole De !**

# Awon Oyinbo Onisowo Agbaiye Nfi Oja Dabira L'okun

## ( Lati owo Ola. Onatade Ololu "Eleti–Ofe" )

EKO—Ni owurọ oni Ọjọ Abamẹta (Satide) ni ogınlọgọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin, ni alawọ dudu ati alawọ funfun yio tọwọ lọ si eti Oku Alaisa

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

Oro Olotu:

# Kinni O Fa a ?

Awọn Yoruba ni ti ko ba nidi obinrin ki jẹ Kumolu; otitọ ọrọ ni. Ṣugbọn kinni o fa ọrọ a ka enia, a ko ka enia ti awọn Alakoso Ijọba Apapọṣe wa l'Eko ti awọn ẹgbẹ oselu Alaake (NPC) dapọ mọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ko le gbe iyọri enia kika na jade?

O to oṣu kẹta nisisiyi ti gbogbo awọn ọmọ ilu Nigeria ti nwọn wa ni ile ati lẹhinodi ti nreti lati mọ iye enia melo ni o wa ilu Nigeria tẹhinti nwọn ti ka gbogbo wa tan.

( Wo yoku loju ewe keji )

**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital £3,181,000

HEAD OFFICE

82/86, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA.
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

DIRECTORS:

SAMUEL LAYIWOLA DUROSARO-Chairman/Managing Director ABDUL AZEEZ OLAYIDE DUROSHOLA-General Manager AYOTUNDE OLATUNDE OSHINIBI

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E. C. 2.

Manager J. F. Burton.

Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegrams Natbaniger ; Londo.
Head Office Representative in London.

E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS

NEW YORK PARIS HAMBURG

30 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, BENNI-CITY, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.

**LAGOS RACE CLUB**

Fourth Day

October Race Meeting

TODAY

First Race at 3 p.m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2.10.0, 2nd £1.10/– and 3rd 10/–.

**Come One Come All.**

Hon. Secretary
Lagos Race Club.



The load is heavy, the ground difficult, the engine is working at full power and yet the driver has perfect control. The light Mercedes-Benz recirculating ball steering is precise to a fraction of an inch. Exact manoeuvering, safe use of marginal space, absolute track steadiness and excellent lock are features of this steering which is just one of the many advantages that all Mercedes-Benz trucks and buses have in common.

**Precision to a fraction of an inch**



MERCEDES-BENZ

Available at:

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (EB) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA.

Sub-Distributors:

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.

ỌRỌ OLOTU:

## Kinni O Fa a?

( O bẹrẹ lati oju ewe kinni)

O dabi ẹnipe nitotọ awọn kan ri o nlo asiko tabi ida-aṣẹ wọn wipe ki nwọn ma gbe irohin ti nwọn ri nipa enia kika na jade nitoripe nkan ti nwọn ri ka nipa awọn ara ilu ọdọ wọn ko dara rara.

Lati inu ọsẹ yi lọ ni awọn alejo onişowo kakiri gbogbo agbaiye lọkunrin ati lobinrin mbọ wa wo ilu wa pẹlu ọja ti nwọn ni lati ta fun wa gẹgẹbi orilẹ-ede tuntun ti o ṣẹṣẹ gba ominira. Ọpọlọpọ ibere nipa ilu wa ni wọn si fẹ mọ.

Ọrọ ti o wa nilẹ yi kiṣe ọrọ ẹgbẹ oṣelu kan; ti nwọn ba bi ọ lere wipe enia melo ni o wa lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati lagba ninu ilu rẹ (Nigeria), iwọ ọmọ ẹgbẹ Alakitkọ (NCNC) tabi ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) tabi ẹgbẹ Alaake (NPC) bawo ni wo wa ṣe ma wo? Bi onugọ.

Ki a ma ṣe tan ara wa jẹ, a ko le ri nkankan sọ ni pato fun wọn nitoripe awọn Alakoso Ijọba Apapọṣe wa ti nwọn ko ara wọn jọ ni Eko ko ju wa ni okun ọrun silẹ lori ọrọ enia kika ti nwọn ti ka lati bi oṣu melo kan sẹhin. Nṣe ni nwọn nfi oni dọla fun wa.

Orişirişi ọrọ ni a si ngbọ kakiri lori ọrọ enia kika na. Awọn kan ni awọn enia kan ti nwọn ko to bi nwọn ti nsọ wipe awọn pọ to ni ko jẹ ki nwọn gbe iyọri gbogbo enia kika na jade fun ara ilu.

O jọ gate, ko jọ gate şugbọn ko fi ẹse mejeji kalẹ. Ẹ jọwọ, ẹ sọ rọna ko ye wa.

# Oro Ilorin Pelu Awon Igbomina Di Oro Suru (3)

## (Lati Owo Olofintoto)

Gẹgẹbi mo ti ṣe alaye fun ẹnyin ọkawe mi wipe nwọn ṣe ipade pataki kan ni Kaduna nigba kan lori ọrọ "a nfẹ ki ẹ pin Ijọba Ibilẹ fun wa" ti awọn ọmọ Igbomina pẹlu awọn ọmọ Ọffa nki gbe le lori lemọ lemọ; ati pe nwọn pe awọn enia pataki bi Minisita Alakoso nkan ọgbin, Mallam Ọkin, Alhaji Sardu Alanamu (tise Aṣoju ni ilu Oyinbo) ki o to lọ si ilu Oyinbo ati awọn ẹnikan ti Ọba Ilorin, Mallam Sulu Gambari yan pe ki nwọn lọ ṣe aṣoju on, si ibi ipade na, nitoripe ọrọ na ti nfẹ di "ỌRỌ KAYEFI" fun Ọlọla Amọdu Bello, Sardauna Sokoto tiṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa, pẹlu awọn Olubadamọran rẹ.

### Ijoba Ibile

Ọkan ninu awọn ọmọ Igbomina, Ọgbẹni A. O. Ọlanrewaju tiṣe Minisita ninu Ijọba Apapọṣe l'Eko ko le sọ wipe on ko mọ nkankan nipa ipade pataki ti Kaduna yi nitoripe nwọn kan on lara nipa rẹ, on paapa si para Kaduna lori ọrọ na bi igba mẹta gbako.

Nwọn ni ki aditi le gbọrọ ni a ṣe nsọ ọ leti ọmọ rẹ. Lẹhin ipade na nwọn ran Alhaji Sule Gaya, tiṣe Minisita Alamojuto awọn Ijọba Ibilẹ kakiri gbogbo Ipinlẹ Ariwa lọ si Ilọrin lati lọ ṣe alaye ipinnu nkan ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa ṣe lori ọrọ na.

Eleyi si ni ẹda ọrọ ti Minisita na sọ fun awọn ti o wa pade rẹ nigbati o de ilu Ilọrin:

"Ọpọlọpọ iwe ẹsun ati waya ni a ri gba lati ọwọ awọn kan ni ilẹ Ilọrin ti nwọn nbere fun adaṣe Ijọba-ara-ẹni tabi ipinlẹ ọtọ fun agbegbe Igbomina, Ekiti ati Ibọlọ. Irohin tilẹ gbilẹ pẹlu pe awọn kan nṣe akitiyan pe ki awọn agbegbe wọnyi yapa kuro labẹ akoso Ijọba Ibilẹ ti Ilọrin.

"Ipinnu Ijọba ti Ilẹ Arewa lori ọrọ irẹpọ larin awọn agbegbe ti mbẹ labẹ awọn Ijọba Ibilẹ han gedegbe laiṣe ani-ani. Oun na si ni lati rii pe gbogbo awọn agbegbe ti mbẹ labẹ akoso awọn Ijọba Ibilẹ nisisiyi fi ẹsẹ mulẹ gbọingbọin laye wọn laisi iyingẹ rara. Eyiyi ni Gomina tẹ mọ ni leti ninu ọrọ ti o sọ lori aga Igunwa rẹ pe Ijọba nri apẹrẹ edeaiyede ni arin awọn agbegbe kan. Ọrọ na sọ siwaju sii pe "o wa ninu aniyan Ijọba lati maṣe fi aye gba iru iwa bayi ati lati duro lori pe irẹpọ ni lati wa ki agbara ati irọrun ba le wa pẹlu.

"Nitori idi eyi ni Ijọba Arewa Naijeria ko ṣe ni ifẹ si dida adaṣe-Ijọba-Ibilẹ tabi Ipinlẹ titun silẹ ni ilẹ Ilọrin. Ijọba fi ye ni pẹlu idaniloju pe ọna ti awọn enia ilẹ Ilọrin fi le ni Itẹlọrun totọ ni ki gbogbo wọn wa ni irẹpọ labẹ akoso Ijọba Ibilẹ Ilọrin. Nipa ọna yi nikan ṣoṣo ni ilọsiwaju ati titẹ ifẹ awọn enia ti mbẹ lori ilẹ Ọba Ilọrin lọrun gbe le wa. Ijọba mọ, yio si ni pẹlu pe gbogbo awọn enia ti o wa lori ilẹ Ọba Ilọrin, laibikita ibiti o wu ki nwọn le ma gbe, ni Ijọba Ibilẹ Ilọrin yio ma hu iwa ẹtọ si laisi ojusaju tabi ẹmi iṣata.

### Ijọba Ko Lodi Si Esun

"Ijọba ko lodi si pe ki a ma mu ẹdun-ọkan wa si etigbọ oun lati ipasẹ awọn aṣoju Ijọba lati Igbimọ Agbegbe titi de Igbimọ Aṣofin ti Ipinlẹ ati ti gbogbo-gboo ni ọna ti o ba tọna. Lori ọrọ yi Ijọba fẹ fi ye mi pe ọna tara ti a file mu ẹdun-ọkan wa si etigbọ oun ni pe ki ẹdun-ọkan na ti ipase Resident ati Ijọba Ibilẹ rin, bẹ gẹgẹ ni o si tun fẹ fi ni lọkan labẹ pe oun yio fi oju anu wo ẹdun-ọkan bayi ti o ba jẹ ododo. Bakanna ewẹ gbogbo ẹsun ti o ba yẹ ki ile-ẹjọ mojuto a ni lati mu u lọ tara si ile-ẹjọ ti o ba tọ si lẹsẹdugbo.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

---

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji (7)

## (Lati owo Omo Abati)

(O bẹrẹ ni ọsẹ to kọja)

Ariwo Ogun Adubi ni ilu Ẹgba le pupọ ju ti Ogun Ijẹmọ ti awọn sọja ti nwọn ni ki nwọn wa dẹruba awọn ara Ijẹmọ bẹrẹsi pa wọn lọ, ti Ọba Alake Gbadebọ ọmọ Ẹfunwunmi ti o wa lori oye nigba na bẹrẹsi jẹ oriki tuntun bayi, "a rẹ Ijẹmọ bi ẹni rẹ'la".

Awọn Ẹgba ko fẹ ki nwọn fi ẹtan ti nwọn fi mu awọn ara Ijẹmọ nigba rogbodiyan ti nwọn mu awọn. Nitorina awọn Ẹgba oko ti o da ijangbọn Ogun Adubi yi silẹ nwọn ko ko o ni ọna kekere; nwọn ko ni ohun ija lọwọ bi ti awọn Oyinbo ṣugbọn nwọn fi oju awọn sọja ti Ọba Gbadebọ ni ki nwọn fi ṣe iranlọwọ fun on ri mabo.

### Ibon Sakabula

Ibọn sakabula ti nwọn fi npa awọn ẹranko bi ọya, aparo ati awọn ẹiyẹ aganran ti o njẹ wọn ni agbado ati gbaguda ti nwọn gbin soko, ni nwọn ni lọwọ gẹgẹbi nkan isọra nwọn si fi ibọn na ṣe ọsẹ pupọ si ara awọn sọja na. Eleyi nikan kọ ni nwọn ṣe, nwọn tun fi ọna ọgbọn miran ba awọn ṣọja na ja. Ọna ti awọn Olorogun Ẹgba na lo pọ pupọ ti a ko le ma ka wọn ni ikọkan ninu iwe yi.

Ninu nwọn nja Ogun yi lọwọ ti rogbodiyan nlọ ni arọko, ti awọn sọja npa enia bi ẹni pa ẹranko bẹni awọn sọja ti nwọn ko si arin ilu Abẹokuta bẹrẹsi hu iwa palapala; nwọn bẹrẹsi yi oko-etile kakiri, nwọn nja nkan gba lọwọ awọn enia ti nwọn ba ri, nwọn si mba awọn obinrin wọn lo pẹlu agbara.

Eleyi jẹki inu bi ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgba obinrin ti orukọ rẹ njẹ Subuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe. Iran Ọba Alake ni obinrin yi; o si jẹ oniṣowo ti o ni owo lọwọ daradara nigbana. Bi o ti ni owo lọwọ ni o si ni mọto-ayọkẹlẹ. O jẹ ẹnikan ninu awọn Ẹgba ti o kọ kọ ra mọto ni igboro ilu Abẹokuta. O ni mọto-ayọkẹlẹ ti o fi ngba afẹfẹ, o si tun ni eyi ti o fi nko awọn ẹru ọja rẹ lọ si awọn ọdọ Oyinbo onibara rẹ ni Ibara.

Obinrin yi kii gbe arin ilu; ibiti o gbe ngbe ni a npe ni Idi-Aba ni Abẹokuta, o si to irin ibusọ mẹfa si arin ilu na. On ni o kọ tẹ ibẹ do ki o to wa di ibugbe fun gbogbo

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# ELETI—OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELGERAM

28 Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI—OFẸ" LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370

VOL. XIV. No 843, SATURDAY, OCT. 27, - NOV 2, 1962


# Agba Di Owo Enyin Kansilo Wa

A FI aye ọrọ Olotu wa ni ọsẹ yi silẹ fun ọkan ninu awọn ọkawe wa, arabinrin kan ti orukọ re njẹ Iyabọ Aya Lawalẹ ti o ngbe Oke-Popo l'Eko, ti o ni on ni ọrọ lati fi ṣi awọn aṣoju wa, awọn kansilọ tuntun ti a ṣẹṣẹ fi idibo yan si ile Igbimọ kekere ti Minisifa ti Eko leti. Iwe ti o kọ na ni eyi:

## Oro Arawa

" Nwọn ni bi a ba nsọkun a ma ri iran, iyẹn ni ọrọ ọmọlẹbi ti mo fe ba awọn Kansilọ wa tuntun ti ilu Eko sọ ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ yi.

"Emi gẹgẹbi ẹnikan ninu awọn obinrin ọloja ilu Eko, mo ki nyin, mo si ba gbogbo nyin yọ ati ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ati Alakukọ. Ẹ ku orire.

"Ọrọ wa di ọrọ arawa, o si yẹ ki a ba ara wa sọ ọrọ ọmọlẹbi, ki a fi ori kori ki a wa ọna bi ao ti ṣe eto ilu Eko ti gbogbo rẹ yio fi toro ti yio fi rọ wa lọrun.

## Itoju Eko

"Lẹhin a ti yan nyin wọle tan, a ngbọ irohin kakiri wipe awọn ẹgbẹ oṣelu kan ti nsọ wipe ọwọ awọn ni eku-ida lati na'wo fun ire ilu Eko wa. Bi ẹ ba sọ wipe kinni yi dara, awọn le sọ wipe ko dara, ki awọn si kọju ara Eko si orun alẹ.

"A ko le sọ wipe iro ni nwọn npa lori ọrọ na nitoripe ko si nkankan ti awọn ọmọ araiye ko le ṣe ninu irin ajo ti a wa yi, sugbọn bi nwọn ba ṣe bẹ, o yẹ ki a fi iṣẹ owọ wọn han gbogbo ọmọ araiye. Sugbọn ko da wa loju wipe nwọn a ṣe bẹ.

"Nwọn ni bi ọdẹ ba ro iya ati wahala ti oju rẹ ri ninu igbo ti o ba pa ẹran tan ko ni fun ẹnikan jẹ. Nitorina mo fi alajọbi bẹ nyin, ẹnyin kansilọ wa tuntun ki ẹ pa ọrọ oṣelu ti si'bikan ki a fa ọtun ati osi wa mọra, ki a to gbogbo rẹ ki ilu le toro daradara.

"Alaga Minisifa ilu Eko, Alhaji Masha, gbogbo awa obinrin ọja ni Eko, Ebute-Mẹtta ati Yaba ba nyin yọ. Itọju ilu Eko di ọwọ nyin".

# {Iwe Si Olotu}

## Gota Kosoko Nfe Atunse

E jọwọ, e gba mi laye lati ba awọn kansilọ wa tuntun yọ ati lati sọ fun wọn wipe a ko ni fẹ lati mọ yọ wọn lẹnu nigbagbogbo, sugbọn a fẹ ki nwọn ma da wa lohun nigbakugba ti a ba ntọka si alebu ti a ba nri ni arin ilu Eko.

Eyiti o jẹ pataki nisisiyi ti ko ba oju mu ni gọta titi Kọsọkọ ni eti Alakoro ni Eko. Ko ye wa si nkan ti o faa, ti omi gọta na ki fi lọ gere sinu odo Ọsa lati iwaju ṣọbu Doherty titi ti o fi de ọja Ebute-Ero tuntun ti nwọn nkọ lọwọ.

Gọta na ko ba oju mu rara; inu wa yio si dun bi e ba le tọka ibe fun awọn oniṣe Minisita ki nwọn ba wa da ọgbọn si i.

Bi ojo ba ti rọ ko si ẹniti o le sọ wipe on gbadun ni adugbo na. Ẹ jọwọ, ẹ gba wa o.

Emi ni,

Ereko Lane, Adunọla

Eko

## Iyoku "Eko Akete Ile Ogbon" Da ?

E jọwọ, Olotu, ẹ gba mi laye lati bere lọwọ opintan nyin, Ọgbẹni Ọlalekan Ọnatade ti o ti ma nkọ itan "Eko Akete Ile ọgbọn" ni ọsọsẹ sinu iwe nyin Eleti-Ọfẹ, pe kinni o ṣe ti Ọgbẹni na ko ṣe kọ ọ mọ nitoripe ninu eyiti o kọ gbẹhin ko sọ wipe itan Eko na ti pari.

Boya ẹ ko mọ wipe gbogbo wa lọmọde, lagba ni a ngbadun itan na, o si tun tọ awọn ọmọ ile-ẹkọ ti nwọn ko mọ itan bi ilu Eko ti ri pẹlu awọn enia inu re ni igba atijọ.

Ninu itan ti Ọgbẹni Ọnatade nakọ ni mo ti mọ bi awọn Kurumọ, awọn ara Liberia, ati awọn Oyinbo Kọra tiṣe de Eko.

E jọwọ, e tubọ bawa gba Ọgbẹni Ọnatade na ni iyanju ki o tun le tesiwaju si lati ma tun kọ itan "Eko Akete Ile Ọgbọn" na siwaju si nitoripe a ngbadun rẹ.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,

Winneba, J. Adediran

Ghana

# Ijoba Aganyin Titun Ja Iwe Irohin Kan Gba

ACCRA—Dokita Kwame Nkurumah, Alakoso Ijọba ilu Aganyin (Ghana) ti gbe ikede kan sode larpẹ yi ninu iwe Ijọba ti nwọn npe ni Gazette wipe Ijọba ilu on fẹ lo iwe irohin kan ti nwọn npe ni "Ashanti Poineer" ti o njade ni Kumasi.

O to ijọ mẹdogun nisisiyi ti Ijọba ilu na ko ti jẹ ki iwe na jade mọ. Ni iwọn nkan bi ọdun keji sẹhin ni awọn alamojuto Ijọba ti yan enia kan pẹlu Olotu iwe na lati ma yẹ nkan ti nwọn ba fẹ tẹ jade wo, sibẹsibẹ awọn alamojuto Ijọba na ni awọn fẹ lo ile-iṣẹ ti nwọn ti

(Wo yoku loju ewe karun

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Omo Eko?

Emi Ayiluka ba ọrẹ mi Ọgbeni Antonio Assaf eniti gbogbo wa ti mọ ni Oyinbo Kọra ni Ọffin l'Eko ri sugbọn ti o ti di ọmọ ilẹ Nigeria lati ọsẹ ti o kọja yi gẹgẹbi ofin Ijọba kan ti a ma nlo fun ajoji enia lati sọ ọ di ọmọlẹbi ni ilu miran, yọ.

Ti a ba ni ki a sọ ọrọ na sibi ti ọrọ gbe wa, ỌMỌ EKO ni oyẹ ni orukọ tuntun ti o yẹ ki a sọ arakunrin wa na nitoripe ilu Eko yi ni nwọn bi i, ibẹ ni nwọn tọ ọ, ibẹ ni o si dagba si.

O yẹ ki a sọ fun Ọba wa, "Ọlọgbọn dori ẹja mu", M··dansiku Adele ni Iga Idunganran, ki o ba wa wa oye kan fun Antonio; bi oye Baalẹ Onitọlọ ni, bi Babasalẹ Ọffin ni, bi Elebute ni, o yẹ ki a ba wa ikan nitoripe on na ti pẹ ni ilu Eko na ko si si nkankan ti nwọn nṣe nibẹ ti ko mọ. O bẹrẹ lori ijo ti nwọn njo ni arin Iga ti o fi de bi nwọn ti nkanṣẹ loju ỌLỌBUN.

Antonio Assaf, ọmọ Onilẹ, Ọmọ Onikoyi, mo ki ọ pupọ, o ku orire, boya emi alara paapa le de ọdọ rẹ ki a jọ fi ọrọ jomi toro ọrọ.

## Olubadan

Ọrọ Ọgbeni Antonio Assaf yi jẹki nniran ọrẹ mi atijọ Ọgbẹni Michael Assaf oni-fọto Gbagi ni Ibadan ni aiye atijọ ti o jẹ wipe ni ilu Ibadan ni awọn obi rẹ ti bi i; Olubadan Abasi Alẹsinlọyẹ kifi ọrọ awọn ẹbi Assaf ṣere rara. Ko si igba ti Olubadan yio kọja lode ile wọn ni Gbagi ti ko ni ya ki wọn.

Gbogbo awa ti a rin mọ Michael Assaf timọ timọ "Ọmọ Oke'Badan" ni a ma npe e, a si gba a ni imọran wipe ki on na ba wọn du oye Olubadan nitoripe o tọ si i. Mo si mọ ọpọlọpọ ọmọ Ibadan ti nwọn fẹ ti i lehin lori ọrọ Oye Olubadan na.

Ọmọ'ya ni Assaf, Ọmọluwabi si ni i.

## Masha

Emi Ayiluka ba Alhaji Abudu Fatayi Masha, ọmọ adugbo Oluwọle ti a ṣẹṣẹ fi jẹ oye Alaga ile Igbimọ Minisifa ilu Eko yọ; mo si tun ba awọn ara Oluwọle yọ nitoripe nwọn ko gba gbẹrẹ ni adugbo wọn rara. Mo ti mọ nwọn ni adugbo na tipe. Ti nwọn ba ni bayi ni awọn yio ṣe bena-ni nwọn a ṣe. Nwọn fẹran a nduro lori adehun pupọ, awọn ati awọn ara Ereko mọ Oke-Arin pelu awọn ara Olowogbowo.

Alhaji Masha, ilu Eko dọwọ nyin. Ẹnyin ara Oluwọle ẹ ku inawo aṣọ, ẹ si ku inawo ọmọ.




## Ijoba Aganyin Ti Tun Ja Iwe Irohin Kan Gba

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

ntẹ iwe na jade pẹlu iwe irohin "Ashanti Pioneer" ti nwọn ntẹ jade nibẹ.

Iwe irohin "Ashanti Pioneer" yi jẹ ọkan ninu awọn iwe irohin ti ọrọ ti wọn ko ba nkan ti Ijọba ilu Aganyin nṣe mu, nwọn si lodi pupọ si eto awọn Alakoso Ijọba na.

# Oba Alake

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

enia nisinsiyi. Ọpọlọpọ ile ẹkọ fun awọn ọmọbinrin ati awọn ọmọkunrin ni o wa ni ibẹ.

## Baptist

Awọn ti nwọn kọ ko ile-ẹkọ sibẹ fun awọn ọmọbinrin ni awọn AMERICAN BAPTIST GIRLS' HIGH SCHOOL, nwọn si si ile-ẹkọ na ni nkan bi ọdun mẹtadinlogoji nisisiyi.

Iṣẹ owo a nra ekurọ, epo ati koko (cocoa) ni Olugbe Subuọla yi nṣe titi ti o fi tẹri gbaṣọ.

Nigbati o ri iwa buruku ti awọn ṣọja ilu nhu si awọn ara ilu rẹ, o dide o bẹrẹ isi le wọn kiri. Tobẹgẹ ti awọn ṣọja na fi mọ moto rẹ, ti nwọn ba ti gburo rẹ ti o mbọ nwọn a ya sa pamọ sinu igbo. Eleyi jẹ ki iwa buruku ti awọn ṣọja na nhu dinku diẹ.

Arabinrin yi, Subuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe, ko duro sidi eyi nikan, o tun lọ si ọdọ Oyinbo Kọmiṣanna (Commissioner) ni Oke Igbein, o lọ fi ẹjọ awọn ṣọja yi sun nipa iwa buruku ti nwọn nhu si awọn obinrin nilu kakiri. Obinrin yi ṣe gudugudu meje ninu Ogun Adubi, awọn ọmọ Ẹgba ko si ni gbagbe rẹ lailai gẹgẹbi nwọn ko ti le gbagbe IYALODE gbogbo Ẹgba, TINUBU ni akoko Ogun Dahọmi.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Oro Ilorin

(O bẹrẹ loju ewe keta)

"Mo ti ronu jinlẹ gidigidi lori ohun ti o ṣẹlẹ ni ilẹ Ilorin, mo si woye pe o tọ, o si yẹ ki nfọ afọmọ Ijọba lori ọrọ yi ki aye ma ba si fun iwa ati si awọn enia ti o wa lori ilẹ Ọba Ilọrin lọna.

Ipinn yi ni pe ao fi Ijọba Ibilẹ Ilọrin silẹ lọkan bi o ti wa fun anfani ati Ilọsiwaju ilẹ na ati ti awọn enia ibẹ".

# Oro Ife

Gẹgẹbi ọrọ ti Minisita yi sọ, a ṣe akiyesi wipe awọn Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa paapa ri gbangba pe ikunsinu wa fun Ijọba Ibilẹ Ilọrin lori ẹsun pe nwọn nfi iya jẹ awọ kan ti nwọn kiṣe ọmọ Ilọrin, ti awọn enia kan ni ilu Ilọrin npe wọn ni "amulo" awọn ; yala ni ile-ẹjọ tabi nipa pinpin nkan anfani ilu si ibikan ki awọn ẹnikan mọ tilẹ ri rara.

Eleyi ni o mu Minisita na sọ wipe Ijọba awọn ko lodi si ẹsun ti o ba jẹ otitọ, ṣugbọn ẹsun na ni lati gba ọwọ Ajẹlẹ (Resident) ti o wa nilu Ilọrin de ọdọ awọn ni Kaduna, nigbana ni awọn yio ri aye lati gbe ọrọ ẹsun na yẹwo bi otitọ ni tabi irọ ni.

Ninu iwadi mi mo ri wipe nitotọ awọn ọmọ Ọffa ati Igbomina ko korira ara Ilọrin ati Ijọba ilu na rara; ilọsiwaju ni nwọn fẹ fun ọmọ ilu wọn. Yoruba ni awọn ọmọ Ọffa ati Igbomina jẹ awọn na si ri bi awọn Yoruba ọmọ iya wọn ti o wa labẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti ni ilọsiwaju to nipa ẹkọ iwe ati nkan anfani si arin ilu.

Mo fẹ ki ẹnyin ọkawe mi mọ nkan kandaju, iyẹn ni aiye ti o ti di aiye ominira. Bi o ba pẹ titi ti a ti nlo ẹru tabi iwọfa, ti o ba di ọjọ kan ẹru na yio ra ara rẹ silẹ nitoripe bi a ti bi ẹru ni a bi ọmọ.

Ẹnyin ọmọ Ọffa ati Igbomina, ẹ ku irọju. Ṣe ẹnyin na wa ri wipe ọrọ yin di ọrọ suru lọdọ awọn alakoso Ijọba Ibilẹ Ilorin ? O digba .


IBI IJOKO AWAMOTO INU AUSTIN S 200 DARA TOBE TO FI NMU ARE AWAMOTO DINKU PUPỌPUPỌ -

O NMU MOTO—WIWA RORUN PELU AISI EWU !



Mọto Austin to lagbara yi tunbọ ṣe alekun wiwa-mọto laisi ewu nitoripe a ti ṣe e dara tobẹ, eyiti yio jẹki iṣẹ rẹ jafafa siwaju si i, ki ere si ma wọle pupọ fun ọ. Mọto S ati T 200 ni inu fifẹ, to si balẹ fun ẹru kiko; jigi iwaju rẹ lagbara, o si njẹki enia riran dada; ojuferese rẹ njẹki mọto ṣe wa fẹhinrin laisi ewu. Bere pe ki a wa a wo ki o ri i.

AUSTIN S 200

(S 200 1½ ton ; T 200 2 tons)

Nigeria Head Office 237 — 241 Igbosere Road. Private Mail Bag 2083, Lagos. Garages at Abo, Akure, Benin, Enugu, Ibadan, Jos, Kano, Lagos, Onitsha and Port Harcourt.

SCOA Motors

# Trade Fair News...

(By Our own Correspondent)

Today is the opening day of the NIGERIAN INTERNATIONAL TRADE FAIR taking place on Victoria Island, Lagos and we dedicated this page for the FIAR News. We understand that about fouty-two foreign Goverments are to be represented at the FAIR and there will be plenty of side attractions.

Invited guests only will be admitted to the fair-ground this moring when the Governor-General, Dr. Nnamdi Azikiwe, will declare the FAIR open, but as from 4 p.m. the general public will be allowed in.

## British Day

The Fair authorities have designated tomorrow (Sunday) as "British Day" at the Fair when the Pipes and Drums of the First Battalion Royal Highland Fusiliers, who are being flown from Malta for the occasion will play fine British and Scottish music.

Mr. Alan Green, M. P., Minister of State in the British Board of Trade who is visiting Nigeria for the Fair will attend the ceremony and with him on the dais will be Alhaji the Hon. Z. B. Dipcharima, the Federal Minister of Commerce and Industry, also the British High Commissioner in Nigeria, Lord Head.

The theme of the British Pavilion is "Nigeria and Britain-partners in progress." Visitors to the Fair will be able to see lots of models illustrating British industry's latest developments.

Yesterday your correspondent was able to see lots of attractions at the British and other foreign Goverments stands. There were the new V. A. 3 "Hovercraft," a new British invention which can travel on water, in the air and on land. The British Pavilion itself is being supplied with light and power by a 300 kilowatt generator.

For a "world tour," visitors can pick up a telephone, dial for any chosen lauguage, and hear a story in Yoruba, Ibo, Hausa, English or French.

## U S A Pavilion

The theme of the United States of America pavilion at the 1962 Nigerian International Trade Fair is "New Skills, New Tools, New Markets," and visitors to the American pavilion will see many exhibits which illustrate this theme.

More than 100 U. S. manufacturers are exhibiting their products in the American building. The products range in size from small hand tools to a completely automated bakery. We understand that the daily production of bakery goods will be donated to Nigerian institutions.

Also on display will be many household products, from large items such as automatic washing machines and clothes driers to electric tin openers.

Otter exhibits at the United States Stand include a demostration of high-speed offset printing, an agriculture exhibit showing how farmers can co-operate to increase efficiency on the farm; demonstration kitchens where Nigerian and American dishes wil be prepared, and a display of American space exploration projects, including a model of Telstar, the communications satelite now in orbit.

## Hong Kong Stand

There are 1,500 quality products from Hong Kong which the Goverment of that country is exhibiting at their Stand at the Fair. The goods carefully selected for the Fair, range from exquisite examples of Chinese craftsmanship to modern products, such as transistor radios air-conditioners and cameras.

The Hong Kong textile industry figured prominetly. On display are wide range of cotton piece-goods, including the popular indigo wax prints specially picked to cater to the sophisticated and selective taste of the Nigerian consumer.

Other articles on the stand are airconditioners, and luggage, plastic articles and aluminium kitchen-ware, umbrellas and electric fans, shoes, cutlery and cosmetices.

At the Stand, I met Mr. Robert S. Sun, Information Officer to the Hong Kong Goverment and other members of Hong Kong Trade Fair delegation who showed me a lot of things.

## Census: American To Assist

Mr. John N. Adams has arrived in Lagos to serve as a data processing adviser in the Census Office. This was announced by the American Embassy, which stated that his services were being provided by the United States Government through the Agency for International Development (U.S. AID).

Mr. Adams, a specialist in data processing systems and procedures, will assist the Census Office staff in recording and tabulating the data acquired in the 1962 Nigerian census. Special IBM tabulating machines are being used

Five Nigerians who are now studying machine processing in America under U S Aid will return next month to assist Mr. Adams in his great work.

## Oni Returns From U K

Among the passengers who arrived from United Kingdom this week were Mr. Alex Ola Oni, Cleansing Superintendent of the Lagos Town Council, and his wife, Wolumotu.

A sports enthusiast, Mr. Oni left this shore about three months ago and visited many places of interest both in England and Scotland.

RECORDS OF THE WEEK

78 R.P.M. at 3/- each
P 82548 H
P 82482
45 R.P.M. at 6/9d each
P 382457 F

PHILIPS
of course...
—the records of the century—
Philips (Nigeria) Ltd.
Head Office: P.M.B. 1136
Apapa
Branch Office: P.O. Box 429

# Oba Alake

(O bere loju ewe kefa)

ti Iyalode TINNBU na yo na'ra fun awon ara ilu re.

Le'inti Ogun yi pari tan Ijoba Gesi l'Eko fi aake kori, nwon ni awon ko ni fun enikan laye ati ma lo ibon sakabula na mo, nwon si gba gbogbo ibon awon ara-oko na lowo won patapata. Eyi je ki awon omo Egba pataki ti o wa ni Eko, awon bi Ologbe J. K. Coker (omo Ajobo), Ologbe S. H. Pease (Elerin), Eric Olawolu Moore (omo Burada) ati awon jakan-jakan be dide si oro na: lehin odun die ni awon Ijoba Gesi na ba tun yi ase na pada ni olukuluku agbe ba tun beresi lo ibon sakabula, sugbon enikeni ti o ba fe ibon Oyinbo oloju meji ni lati gba iwe-ase. Ofin yi ni o wa nile ni Nigeria titi di ojo oni.

(Iyoku di ose ti mbo)

## Awon Oyinbo Onisowo A g b a i y e

ni erekusu Eko lati lo wo orisirisi oja ati awon irinse ti awon agbe fi nroko ati nkan ti a fi nkole pelu moto-ayokele ati akera ti awon Ijoba Oyinbo ajoji ko wa si ile yi lati wa fi pate.

Gomina-agba, Ọlọla Nnamdi Azikiwe ni nwon pe ki o wa si ibi ipate-oja gbogbo agbaiye na.

Nigbati mo de ibi ipate-oja na ni ana temi pelu awon oniwe irohin lati Eko pelu Ibadan, a wo yanu ni gbogbo awon nkan ti nwon fi han wa nibe.

## Amerika

Ibi ipate-oja awon Ijoba Oyinbo Amerika ni nwon ko ma gbe wa. Gegebi enyin onkawe mi ti mo wipe ilu agbe ni ilu awon Amerika, nwon fi opolopo ero ti nwon fi nroko han wa pelu ero ti nwon fi nse onje ati awon nkan beebe ki a to wa lo si ile ipate awon Ijoba Geesi.

## Geesi

Awon Oyinbo Gesi yi ti fi ojo ola tise ojo Aiku sile fun ojo ti awon yio "taka" wipe "aja lo ni eru, iro ni pepo npa." Nwon ti fi oko aropilen ko awon soja onifere, ti iru won ko sere nile yi ri, wolu lati wa fon fere fun wa lojo won na ti nwon pe ni Ojo Ijoba Gesi "British Day." Bante ni awon Oyinbo soja na yio fi se sokoto, ti nwon yio san sidi.

## Russia

Bi o ba fe mo bi aiye ti nlo si lori gbogbo nkan ero ti nmu idera ba ara aiye ki o lo si ile ipate - oja awon Oyinbo Ijoba Rossia (Russia). Awon Oyinbo yi ko se fi owo ro sehin ninu awon ero alagbara. Oju mi ri nkan pupo nigbati a de ile ipate-oja won.

## Oga Oyinbo Aka'nia De

Irohin ti a gbo loru ana ninu ile ise wa ni ti Ogbeni John N. Adams, Oga Oyinbo K'ania-ka'nia kan ti awon Ijoba ilu Amerika fi ranse si Ijoba Apapose pe ki o wa ran awon lowo, ki o ko nwon bi nwon ti nlo ero lati fi mo enia melo ni o mbe ninu ilu kan.

A tun gbo wipe awon Ijoba Amerika na ti mu awon enia marun ninu awon omo wa lo si ilu Amerika na lati lo ko won ni ona ise a nfi ero ka enia na, awon marun na a de ninu ose ti mbo yi lati wa ran Oyinbo yi lowo ninu ile ti nwonti nse ise ak'ania (Census Offiice).

A dupe lowo awon Ijoba ilu Amerika, a tete fe gbo iyori awon enia ti nwon ti ka, ti a ko mo ibiti nwon fi iyori enia-kika na si di ojo oni.

## Ogbeni Oni Ti Ilu Oyinbo De

Ninu awon ti o ba oko ilu Oyinbo gunle si Apapa ni ijeta ni Ogbeni Alex Ola Oni, oga kan ninu ile ise Minisita l'Eko, eniti o ti lo si ilu Oyinbo fun ilosiwaju ise re lati iwon nkan bi osu meta, on ati iyawo re ti nwon npe ni Wolimotu.

Ogbeni Oni, eniti gbogbo awon ore ati ibatan re mo adape oruko re ni "OGA" je enikan ti o feran ere bolu - afesegba pupo, iru si ni kii won nibikibi ti nwon ba nsere bolu yi.

Ki o to pada wa sile opolopo ibi pataki pataki ti o je mo ibi ise re ni o de ni ilu Oyinbo na.

A ki awon ore ati ebi "Oga", awon bi Ogbeni Taju Thompson, Iyafin Batili Oni, Amope Oni, Abeni Oni, Muniratu Aduni ("Wundia Offin") aya Balogun ati awon ebi Agunbiade pe nwon ku afojuba.



Iru moto-ayokele tuntun yi ni awon Oyinbo Ilu Ijoba Gesi mu wa si ile Nigeria ni Eko lati wa fi pate oja won ni Okun Alasia. Nwon npe moto na ni MGB British Sports Car.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU) OLA ONATADE
15, Kosoko Street, Lagos.